OWE
Olowo ki i ma a jẹ orogan ki iwọfa o tun ma a jẹ agunmatẹ.

# Irohin Yoruba

VOL IX No. 450 MONDAY FEBRUARY 22, 1954 KOBO KAN (1d.)

E MA A POLOWO
Oja Nyin Sinu
Iwe Irohin Yoruba

# IKORIKO BI OMO ENIA

LUCKNOW-- Eyi ni aworan ọmọ ikoriko kan ti nwọn npe ni Ramu, eyiti nwọn ri gbe ninu ag nju igbo kan ni ilu India ti o wa ni Ile-Iwosan, kọbọ-kọbọ ni awọn enia nsan lati fi wo o. Ọpọ awọn enia nwo o pẹlu iyanu nigbati awọn dokita ati awọn ti mba wọn ṣiṣẹ bọ aṣọ kuro lara ọmọkunrin na ti nwọn si wan an si hobo ti nwọn si ṣi ete rẹ si oke ki gbogbo enia le ri i pe o jọ t'ẹranko.

Ọmọkunrin-ẹranko na di ọmọ ọdun mẹsan, aisan ti ko arẹ ba a ki nwọn to ri i gbe ninu aginju igbo. Egbo, iṣaka ati apa oju-ẹgbo gbogbo ni o kun ara rẹ, irun ori rẹ ta koko ati pe ara rẹ si ioro. Nwọn ti bẹrẹsi fi ẹran sise ati asaro ati awọn omi inu awọn eso bi ọsan-orombo bọ ọmọkunrin-ẹranko na. Ko nsọrọ rara ṣugbọn o ma a nsọkun, o si nkun ibi Aja. Nigbamiran yio fẹ lati bu awọn ti o nṣe tọju rẹ jẹ. Bi o ba ti gbọ orun ẹran tutu ti nwọn pese lati fun un jẹ ara rẹ a ya, laiti fi oju gan-ni ẹran na.

Bi Koriko ni o njẹun, yio kọkọ fọ egun inu ẹran ti nwọn ba fun un lati jẹ ki o to gbe gbogbo ẹran na mi lẹkanṣoso. O nfi ahan la omi bi Aja. Awọ ẹsẹ rẹ fẹlẹ pupọ bi ti ọmọ-ọwọ ni, eyi fihan pe ko rin ri. Awọn igbọ-wọ rẹ jọ ti ẹranko. Nwọn ti fun un ni ipara fun iwosan, o si le na ọwọ ọtun rẹ nisiyi ṣugbọn ọwọ osi rẹ ṣi gan.

Ọlọla Phillip Manson-Bahr oyinbo Ọjọgbọn [ British Scientist ] ti o yẹ Ramu wo si sọ pe ọmọ na ko ni le rin daradara.

Nwọn ngbero pe, laipẹ nwọn a mu u lọ si agbo ẹran Lucknow, nwọn a si fi si ago awọn ikoriko lati tun fi wo o bi iwa rẹ ko ba iti yipada pẹlu ti awọn ẹranko-ikoriko.



# Solomon Akintola D'Oluogbe

OGBOMOṢO – Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Ọgbẹni Solomon A. Akintọla ti iṣe Baba Ọlọla S. L. Akintọla (Central minister of Health), Gbakeji Olori Ẹgbẹ Action Group ṣe alaisi ninu ile rẹ ni Ogbomọṣhọ nigbati o di ẹni ọgọrin ọdun laiye. Ẹsẹkẹsẹ ti gbogbo ilu ti gbọ ni nwọn ti bẹrẹ si wọ wa ki awọn ẹbi ati awọn ọmọloku na.

Ni ọjọ keji ni nwọn ṣe isin ikẹhin fun un ni Ṣọọṣi Kini Ijọ Awọn Onitẹbọ ni [First Baptist Church] Oke'lerin, Ogbomọṣhọ ni deede agogo mẹta ọsan, awọn ọpọ enia dabi omi, Ẹni-ọwọ Alufa Ige ni o ṣe alakoso eto isinku na o si sọ ọrọ iwuri pupọ nipa iwa ati iṣẹ ologbe na bi o ti jẹ olufọkansin si ati bi o ti ni inu rere si t'ọmọde t'agba. Lẹhin isin na ni gbogbo enia Ijọ, ẹbi, ọmọ ati awọn alabaṣẹye gbogbo ba tẹle oku na lọ sin.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ogunlọgọ Ọlọla ati Oloye ti o wa si ibẹ bi awọn alabakẹdun ati alabaṣẹye ni Dokita Akinọla Maja, Oloye Baba Eko ati Baba Ẹgbẹ Ọmọ-Oduduwa, Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Action Group ati Alamojuto Ijọba Iwọ-orun, awọn Aṣoju Igbimọ Ijọba Iwọ-orun ati ti Apapọ Igbimọ-Nla Aṣofin Nigeria. Awọn Aṣoju Ọba Alake Abẹokuta, Ọba Ọni Ifẹ, Ọba Alafin Ọyọ, Ọba Adele Keji Eko, awọn Oloye onifila-funfun Eko.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kokandinlogun oṣu yi kan na ni nwọn ṣe iṣade ọfọ oku na ninu ṣọọṣi kanna, awọn ẹro si tun pọ bakanna bi ti ọjọ isinku. Oniwasu na si tun sọrọ pupọ lori igbesi aiye oluogbe na, lẹhin isin, gbogbo awọn enia si ba awọn ọmọ oku lọ si ile. Nwọn si ṣe oku na gbakagbiyan, Aiye gbọ ọrun mọ.

Ẹhin baba a dara o "S L A" tiwa ọwọn, Ẹ ku aṣẹhinde, ki Oluwa f'awọn ọmọ rere gbẹhin ẹnyin na o.



Ọlọla S. L. Akintọla

# Abudu Karimu di Lemomu Agba

EKO - Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni awọn ẹbi Nollah ati awọn agbagba Musulumi Eko ṣe ipade pataki kan lati yan Lemọmu agba si Mọṣalaṣi Jimọ Eko lati rọpo Lemọmu agba Tijani Ibrahim ti o jalaisi ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọ.ọ karun oṣu yi. Nigbati nwọn ṣe aṣaro na s'ọtun s'osi tan, nwọn ri i pe Lemamu Mọṣalaṣi Oko-awo, Abudu Karimu Nollah ni o tọ si, nwọn si panupọ yan an si aye Lemọmu agba fun Mọṣalaṣi Jimọ Eko na.

Nwọn yio si we lawani oye Lemọmu agba na fun un ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keje oṣu ti o mbọ yi, nwọn yio si mu u lọ si iwaju awọn agbagba Mọṣalaṣi Jimọ na.

Nwọn bi Lemọmu agba ti nwọn yan yi ni ọdun 1880 ni Eko, l'Eko na ni o si gbe kọ ẹkọ. Lehinti o ti fi itara ṣe ẹsin musulumi larin Eko ni ọrọ̀-rin aye ati fun ọpọlọpọ ọdun, ni awọn alamojuto mọṣalaṣi Oko-Awo ba yan an si aye Lemọmu Oko-Awo, ori aye yi na ni o si wa titi di aseko ti nwọn fi yan an si aye Lemọmu Agba Mọṣalaṣi Jimọ Eko. Oye a mọri o.



Ọgbẹni Abudu Karimu




# Oyinbo Kan Lu Ofin Owo-Ori

YABA-EKO--Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Ọlọpa mu ẹsun Oyinbo kan ti iṣe Alamojuto Apapa Club wa si iwaju Adajọ-Kekere Isaac John ni Ile-idajọ kẹrin ti Yaba, pe ko da Iwe eto Owo Ori [Tax Form 6] ti awọn Olowo-Ori mu fun un lati kọ awọn orukọ ti o mba a ṣiṣẹ sinu iwe na pada, ki nwọn ba le mọ iye owo ori ti nwọn yio gba lọwọ awọn oṣiṣẹ rẹ na fun ọdun 1953/54. Lọya Wickliff ni Oyinbo Alamojuto Apapa Club na

Wo oju-ewe kẹrin

